**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**ẸLẸ́RÙ IBI, GBÉ ẸRÙ RẸ (4)**

**OṢÙ KẸ́FA, ỌDÚN 2026**

Ìwé Mímọ́ Kíkà: Ẹ́stérì 7

Ìjẹ́wọ́: Òwe 26:27

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sí Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Ìwà-ìkà ìyówù tí àwọn agbára búburú ilé bàbá mi gb'èrò, túká báyìí, ní orúkọ Jésù.
6. Olúwa, jẹ́ kí ìkà gbé àwọn ẹrù búburú tí wọ́n pèsè fún ọjọ́ iwájú mi, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ìwà-ìkà tí wọ́n jókò pète-pèrò, tí wọ́n ṣe lòdì sí ayànmọ́ mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
8. Olúwa, jẹ́ kí a mú àwọn ìkà nínú iṣẹ́ búburú wọn, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, jẹ́ kí ìwà-ìkà fún ìkà l'ọ́rùn pa, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo ahọ́n tí ìwà-ìkà tìlẹ́yìn lòdì sí ayànmọ́ mi, gba ìpalẹ́numọ́ nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
11. Olúwa, jẹ́ kí okùn ìwà-ìkà tó lòdì sí ayànmọ́ mi di ṣẹkẹ́ṣẹkẹ̀ ìdájọ́ fún ìkà, ní orúkọ Jésù.
12. Ọwọ́kọ́wọ́ ibi tí wọ́n nà sí ògo mi, gbẹ báyìí, ní orúkọ Jésù.

13. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo ètekéte ìkà pa àwọn tí wọ́n ṣe wọ́n, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo pẹpẹ ibi tó n sọ̀rọ̀ lòdì sí ayànmọ́ mi, ṣubú sí abẹ́ iná, ní orúkọ Jésù.
15. Olúwa, jẹ́ kí òkùnkùn gbé àwọn tóni wọ́n mìn, ní orúkọ Jésù.
16. Àsọkágbá ibi ìyówù tí wọ́n kọ nípa ọjọ́ iwájú mi, di àtúnkọ lòdì sí ẹni tó kọ ọ́, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo ètekéte ibi tí wọ́n ṣètò láti ṣiṣẹ́ lòdì sí ayànmọ́ mi, bàjẹ́ báyìí, ní orúkọ Jésù.
18. Olúwa, jẹ́ kí ìkà gba ìjákulẹ̀ nípa ète búburú wọn, ní orúkọ Jésù.
19. Àkọsílẹ̀ búburú ìyówù tó n sọ̀rọ̀ lòdì sí ayànmọ́ mi, jẹ́rì lòdì sí ẹni tóni ọ́, ní orúkọ Jésù.
20. Bàbá, jẹ́ kí ìkà ṣubú sínú iṣẹ́ aburú wọn, ní orúkọ Jésù.
21. Gbogbo ìwà-ìkà tí àwọn ọ̀tá mi rólágbára láti gbógunti ayé mi, di asán nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
22. Olúwa, jẹ́ kí àwọ̀n ìwà-ìkà tí wọ́n yàn lòdì sí ayànmọ́ mi fàya, kí ó sì pa ẹni tó ṣe é run, ní orúkọ Jésù.
23. Ìṣígun dìde búburú ìyówù tí wọ́n pèsè fún ọjọ́ iwájú mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
24. Bàbá mi, jẹ́ kí ìkà rì sínú odò búburú wọn, ní orúkọ Jésù.
25. Gbogbo ètò búburú tó farasin sábẹ́ àṣẹ ibi lòdì sí ayànmọ́ mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
26. Olúwa, jẹ́ kí àwọn ohun-ìjà ìwà-ìkà tí wọ́n yàn lòdì sí ayànmọ́ mi tapadà, ní orúkọ Jésù.
27. Ọwọ́ òkùnkùn ìyówù, tó nrú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ búburú dìde lòdì sí ayànmọ́ mi, pàdánù iṣàkóso rẹ, kí o sì tapadà, ní orúkọ Jésù.
28. Gbogbo ètò ìkà tó lòdì sí ayànmọ́ mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
29. Gbogbo pámpẹ́ ibi tí wọ́n dẹ fún ọjọ́ ọ̀lá mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
30. Ètekéte ibi ìyówù tó n lépa ayànmọ́ mi, mú ẹni tó ni ọ́ so, ní orúkọ Jésù.
31. Gbogbo ìwà-ìkà ìkọ̀kọ̀, tó nró ìgbóguntì lágbára lòdì sí ògo mi, kí àṣírí rẹ tú, kí o sì wólulẹ̀, ní orúkọ Jésù.

32. Májẹ̀mú-kí-májẹ̀mú tó n sọ̀rọ̀ búburú lòdì sí òwò/iṣẹ́ mi, tapadá, ní orúkọ Jésù.
33. Gbogbo àyídáyidà tí ó jinlẹ̀ sínú ìwà-ìkà, tapadà, ní orúkọ Jésù.
34. Gbogbo ètò ìkà tó farasin gẹ́gẹ́ bí ẹ̀rín láti kó idàrúdàpọ̀ bá ọ̀la mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
35. Gbogbo àkọsílẹ̀ búburú tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ìgbéyàwó mi, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
36. Ìṣètò sátánì ìyówù tí àwọn òṣíṣẹ́ ibi rólágbára láti ba ìgbéyàwó mi jẹ́, túká báyìí, ní orúkọ Jésù.
37. Gbogbo ìwà-ìkà tí wọ́n ṣètò, tí wọ́n ṣe sí òwò/iṣẹ́ mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
38. Gbogbo ahọ́n búburú tó n dúkokò mọ́ ayànmọ́ mi, gba ìpalẹ́numọ́, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
39. Ọwọ́kọ́wọ́ ibi tí wọ́n nà lòdì sí ayànmọ́ mi, gbẹ báyìí, ní orúkọ Jésù.
40. Gbogbo èròngbà ìkà fún ayànmọ́ mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.